# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 90    SATURDAY, MARCH 29, 1924.    Fourpence.


1 APR 1924 LAGOS


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374.    Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Feeds of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."

---

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

## J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laila, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.





Awọn Oyinbo Onișowo yi nransẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' olwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ransẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nransẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ..ikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun ..ẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu ..awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

**M. D. MARTINS**

23, SCALE SQUARE, LAGOS.

Ọgbeni yi jẹ ẹniti o nşe ọti orişirişi. Ginger Ale, Şile mẹta abọ (3/6) fun Doz. kan ninu Igo Beer, ati Şile mẹta (3/-) fun ẹniti o ba fẹ ra pupọ bi Dozen marun (5 Doz) ati ju bẹ lọ.

Lemonade bakanna, Cider Champagne bakanna Soder Water ninu Igo kanna Şile kan ati Nain (1/3)

O npọn ọti ni Jebba Street, Ebute Mẹta.

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

**HAMBURG, Neurwall 16/18.**
**Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

ẸNIKEJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

## ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ), l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Ọsu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Ọsu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

DẸDẸ O, LAMỌMỌ TO NM'EGBO OJUGUN.

A gbọ pe ni *Sunday* to kọja, awọn Ijanma f'ohun ṣọkan lati jẹ ki Issa Aburo Lemọmu Braimọ (Ologbe) ma ki wakati mararun fun awọn Musulumi to wa ladugbo Mọṣalaṣi nla ti a ṣi lọṣẹ to kọja; awọn Irun ti a sọ pe ki o ma ki fun awọn enia na niwọnyi :—

Asuba, Ayila, Alasari, Magaribi ati Lişayi, ki o si ma ti'lẹkun lẹhin ti o ba buge; a gbọ pe ẹnikan ti o njẹ Fasasi fẹ da rugudu miran silẹ nipa pe o ni on yio ma gba ọrọ Issa sọ ninu Mọṣalaṣi gẹgẹbi a ti sọ fun ni, ṣugbọn lọgan ni a sọ pe awọn enia le jade

IPADE IGBIMỌ SUN M'ETI'LE.

Ipade Igbimọ Aṣofin yio wa l'arọ ọtunla. Ninu awọn ofin ti nwọn yio ṣe nibẹ ni ofin ti owo oṣoṣu (*Pension*) ti a o ma fun Ọgbẹni Henry Carr Balẹ Ilu ẹniti o nfẹ sinmi ninu iṣẹ lẹhin igbati o ba lo kye *leave* rẹ tan.

A gbọ pe Ọgbẹni wa na npete lati lọ si Ilu Oyinbo ninu oṣu *May* ọdunni.

MA FI TIRẸ KỌ MI L'ỌRUN LO DA F'EKAN ON OWU.

A fẹ ki awọn kan ti nwọn kọ'we si wa lati Ago Ọbà Abẹokuta, ninu eyiti nwọn sọrọ Alufa C.M.S. kan ti o wa lẹnu iṣẹ ni Ọfada mọ pe a kọ lati gba ohun ti nwọn kọ sinu Iwe na gbọ, ayaṣebi nwọn ba kọ iwe na lọna tara, ki nwọn fi oruko ti nwọn njẹ tọtọ si i, ati Adugbo wọn, bi bẹkọ asan ni iwe ti nwọn kọ, asan si ni iregbe wọn pẹlu.

BALẸ ILU SỌ "BOTO" L'ỌRỌ.

Asọye ti Ọgbẹni wa Henry Carr I.S.O. Balẹ Ilu sọ ni Ile Iwe Giga ti awọn C.M.S. (*C.M.S. Grammar School*) lori "Ero Ara Ilu" (*Public Opinion*) ni *Thursday* ọsẹ to kọja, dun mọ gbogbo awọn to wa nibẹ jọjọ: ohun ti o dun ni nibẹ ni pe nigbati Ọgbẹni na pari Asọye rẹ tan, aye ko si fun Alaga Ipade na Ọgbẹni Eric. O, Moore Ọlọla lati jẹ ki awọn enia sọ si ijimi ọrọ Balẹ si.

Ṣugbọn a dupẹ pe nigbati a lọ ki Balẹ na ti a si sọ ẹdun yi fun u nijọ keji, o ṣe'leri lati tẹ Asọye na fun anfani awọn to ba nfẹ ẹ.

ẸKỌ GBE NI NI'YI, ỌGBỌN GBE NI GA.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Omugọ tabi ọpe jẹ orukọ ti ẹnikẹni ko fẹ ki a mọ on mọ, gbogbo enia li o korira orukọ na, gẹgẹ bi awọn Kiriyo tabi Onibuku ti korira Judasi ole.

Nigbati a ba fẹ ṣe isami tabi isin i-b'omi-le-ni-l'ori (*Baptism.*) orişirişi orukọ nlanla ni a fi nsami fun awọn Onigbagbọ nibẹ. Jeremiah, Habakuk, Zechariah, Lasarus, Ezekiel, Malachi, Abraham jẹ orukọ ti pupọ ninu awọn Onigbagbọ ọsan-gangan fẹran ju; bi eni wipe orukọ nla wọnni, eyiti pupọ ninu wọn ko le pe daradara, eyiti nwọn ko mọ itumọ rẹ, ani eyiti pupọ ninu wọn ko tilẹ ni itumọ rara, ni işika tabi kọkọrọ Ijọba Ọrun.

Lẹhin ti ẹlomiran ninu awọn Hezekiah wọnyi ba ti sami tan pẹlu orukọ girimọkayi wọn, bi ẹnikan ṣeşi pe wọn ni orukọ abisọ wọn, oluwarẹ da'ran niyẹn, nwọn a wipe o ba orukọ wọn jẹ.

Ṣugbọn, bi nwọn ti korira orukọ baba nla wọn, ti nwọn si fẹran gba-kan-nşubu orukọ oyinbo to

yi, a koi ti ri ẹnikan ṣoṣo pere ti o ni on fẹ Judas Iskariot bi orukọ isami; bẹ gẹgẹ si ni ẹnikẹni ko fẹ ki a pe on ni Omugọ tabi Gọngọṣu, odidarẹ.

Ẹniti Ọlọrun yọda ọmọ fun, ti o si tiraka-tiraka titi, ọjọ ririjẹ, ọjọ airijẹ, lati ran ọmọ na lọ si Ṣukuru, Ile-iwe kekere ati giga, oluwarẹ nfẹ ọlọgbọn ọmọ ni, a ko wipe gbogbo ẹnikẹni ti ko ba mọ iwe ni ọbọ tabi lagido o; nitori ko di igbati enia ba gbọ ede oyinbo, ti o si mọ itumọ "Kọnkọnbiliti" ki o to ni ọgbọn tabi lākaye: ẹla li ọrọ.

Ṣugbọn nigbati Baba tabi Iya ran ọmo lọ si Ṣukuru, ti o si nná owo iyebiye le e l'ori ni oniruru ọna, ti ọmọ na ko si mọ iwe to bi o ti tọ ati bi o ti yẹ, ibanujẹ nla ha kọ li eyi jẹ fun awọn Obí (*Parents*) rẹ? Nitotọ, ọmo miran wa ti ori rẹ ti d'ọta, ti gbogbo iwe ti o nkọ dabi irugbin ti a fún si ori apata, eyini ko nṣe ẹjọ Oluko rẹ, ṣugbọn eyiti o nfi oju si iwe rẹ—papa, li ode ti oni nkọ, kili o mọ?

O ṣe! Aiye nlọ, a ntọ ọ. Ni lailai, ọmọ ti o ba jaja ri ẹni ran on lọ si Ṣukuru oni-kọbọ-kan (*Elementary Schools,*) titi o fi ka Iwe karun (Std. V.) ọmọ na ṣe ori're; eyiti o ba de Ṣukuru giga (*Secondary Schools,*) iyẹn ti di Oyinbo patapata. Loni nkọ? Ọmọde miran ti o nka Iwe keje (Std. VII.) ni Ṣukuru giga, ko le tu bata ẹsẹ oni'we kẹrin (Std. IV.) lailai ninu Iwe. Dipo eyiti ẹkọ iba fi ma lọ siwaju, nṣe li o nr'ẹhin Li ògúnná; ofo, ọjọ keji ọjà.

Ki a tilẹ fi awọn ọkunrin silẹ, ki a darukọ awọn obirin diẹ ti o dagba, ati diẹ ti ko dagba ju ninu awọn ọmọ Ile-iwe Eko yi kanna ni lailai, li aika awọn ti o ti pa ipo dà. Iwe ti Mrs. I. Oluwọle, iyawo Biṣọpu, ti Mrs. S. R. S. Williams ti oke Olowogbowo, ti Mrs. Z. A. Williams, ti Mrs. Marsh, iya Mr. Marsh ti Marine Department, ti Mrs. J. S. Williams ti Ebute Mẹta, ti Mrs. W. T. G. Lawson, ẹgbọn Ejo-ngboro, ti Mrs. Kitoyi Ajasa, Mrs. C. Ọlajumokẹ Ọbasa ati Mrs. Abimbọla Gibson aburo rẹ, ti Mrs. J. Bagan Benjamin, Mrs. Shitta-Akisan, Mrs. Louisa Byass, Mrs. Banjiro George ati awọn obirin diẹ miran mọ̀ li akoko ti nwọn wa ni ọmọge ṣọlọ-ṣọlọ-ṣọlọ, ti nwọn si nlọ si Ṣukuru ni ilẹ yi ni ọdun jọjọ sẹhin, melo ni a le fi ọwọ sọ'ya nipa wọn bẹ ninu awọn *Girls* isisiyi?

Ṣugbọn bi ọwọ awọn *Girls* wọnyi ba tẹ Kalamu (*Pen*) ko le gba wọn ni iṣẹju mẹwa lati kọ Wosika bi eyi:—

MY DEAREST LOVE,

Believe me, *dear*, I cannot sleep the whole of last night. I kept on dreaming about you.

Papa and Mamma are still relentless in their objection against our match; they say I am too young and that you are very frivolous. Auntie says she does not like you at all because of your drinking habit and extravagant disposition. Don't be upset on that account, *dear*, I will disregard their warnings—it's all rubbish.

Kindly send me a sum of Five pounds (£5 os. od.) as soon as possible, to buy some dressing materials including silk stocking obtainable at C.W.S. Shop.

*Darling*, expect me this evening. I shall be there by 8 p.m. or, would you like to come over then as Mamma is sure to be out by that time; Papa, of course, as you know, seldom returns home every night before 12 o'clock midnight.

Love and kisses from your own

BECCA.

Itumọ rẹ ni rafanda ni eyi:—

Olufẹ mi ọwọn,

O le gbagbọ wipe titi ilẹ fi mọ, ng ko fi oju mi kan ōrun. Iwọ ṣā ni mo fi nla'la.

Awọn "ara-'le-rẹ" njẹ ijanu sibẹsibẹ, nwọn n ng ko gbọdọ fẹ ọ, nitoripe ng koi ti dagba to lati ni ọkọ, ati wipe iwọ papa jẹ oni-were-were enia. Gbogbo rẹ ko tilẹ dun mi bi ti Anti yẹn kẹ, o n' ọmuti ati oninakuna ọmọ ni ọ. Maṣe fi isọkusọ ti wọn yẹn si ọkan rara, apò ara wọn ni nwọn nsọ ọ si.

Sa ba mi wa Pọnwun marun (£5 os. od.) kan niba jaba lati fi da aṣọ, ati lati ra ibọsẹ ṣẹda kan ti o ṣẹṣẹ de si ti C.W.S.

Ma reti mi li agogo mẹjọ alẹ yi, ti o ba si wu ọ, o le wa si ile wa nigbana, nitori Iya yio lọ si ode li akoko na, bi agogo mejila oru ko si lù, iwọ na mọ wipe o ṣoro ki Baba mi to wa ile—nwọn pọ li ọwọ orò.

Emi ni olufẹ rẹ,

BẸKA.

Irufẹ iwe bayi yá si ẹlomiran ninu awọn *Girls* isisiyi lọwọ pupọ lati kọ; asinwa-asinbọ, lẹhin ti nwọn ba fi ori-kunkun gba Oruka-arede tan, nwọn a bẹrẹ si fi igi imu sọkun bi ẹlẹgbara; ṣugbọn, ẹpa ko ba oró mọ—*for better, for worse.*

Ng ko sọ wipe irufẹ Lẹta tabi Wosika bayi li o nfa ẹkọ sẹhin li Eko; agẹ ẹdọ! Ng ko sọ ohun ti o jọ bẹ rara: ṣugbọn iwe ti awọn Oluko nkọ-ni ni Ṣukuru Eko nisisiyi ko mo iyan lori. Ko nṣe ẹjọ awọn Olukọ papa, ofin (*Education Code*) ni nwọn ... ntẹle. Diẹ ninu ofin yi fẹ atunṣe nitori anfani awọn ọmọ wa, ati nitori ilọsiwaju ilẹ Enia Dudu ni iwọ-ōrun Afrika.

Ẹda'lu ni ṣe'lu. Ni ilu Oyinbo, ti ọmọde ba pẹ diẹ lẹhin iṣẹju marun ki o to de Ṣukuru, nwọn le ti ilẹkun mọ ọ si ode, ki o ma ri aye wọle, ṣugbọn âṣa buruku gbā li o jẹ fun wa nibi.

Ni Ile-iwe giga ti obirin, *C.M.S. Girls Seminary* ati ni ibomiran pẹlu, bẹni a gbọ wipe nwọn nti ilẹkun mọ ọmọ ti o ba pẹ lẹhin diẹ si ode, ilẹkun na yio si ma wa ni títì di nkan agogo mọkanla tabi ju bẹ lọ. Aṣà yi nfun awọn ọmọde li aye ati ma rin kiri ilu bi agutan ti ko ni oluṣọ, nwọn ko si le ri aye kọ iba ẹkọ diẹ ti a nkọ wọn ni Ile-iwe.

Gbogbo ọmọde ni lati ma tete de Ṣukuru li akoko, ẹniti obi tabi alagbatọ rẹ ba si da duro diẹ

ni ile, ni lati gba iwe lọwọ wọn wa si Şukuru fun Olukọ wọn, bi bẹ kọ, Ẹgba-atori mẹta tabi mẹrin lọwọ wọn yio şe işẹ daradara pupọ ju ki a ti ilẹkun mọ wọn si ẹhin ode lọ--papa, nigbati nwọn ko jẹ gbese owo Ile-ẹkọ (*School Fees*).

Ẹgba Atori tabi Ọşunşun to dara ti nwọn ko nsaba fi na awọn ọmọ wa ti ko mo iwe wọn ni şukuru mọ nisisiyi bi ti lailai ko dara pẹlu, o yẹ ki a ma fun wọn lẹgba diẹ diẹ lọwọ tabi nidi lẹkọkan—eyi ko buru rara.

Ẹkọ Ile-iwe isisiyi ko ga to, họlide (*Holidays*) tabi isimi pẹlu ere şişe (*Sports*) si pọju, pāpa 'arin awọn Şukuru giga. Isimi ọsẹ kọkan lẹhin işẹ oşu mẹta pere laika isimi oşu kan ti akoko ọjo. *June Holidays*, oşu kan ti akoko ọdun, *December vacations*, laika isimi pẹ-pẹ-pẹ miran ti Satide-Satide, ati bi ki ara olukọ ma da, ki nwọn ma si şe Şukuru ọsan, irufẹ eyiti a gbọ pe o şẹlẹ ni *C.M.S Girls' Seminary* ni ọsan ọjọ Jimọ keji ọhun, *Friday the 14th instant*, nigbati ojojo nşe Miss Waite, Oyinbo Alabojuto Ile-ẹkọ na.

Isimi ọsẹ mẹrin ko pọju fun akoko ojo, ọsẹ meji to fun akoko ọdun.

Owo Şukuru (*School fees*) isisiyi pọ ju fun awọn makunnu lati san, o yẹ ki a din wọn ku diẹ diẹ, iyẹn to ba jẹ wipe otitọ ni a nfẹ ki gbogbo ọmọ wa mọ iwe daradara.

Itunmọ ti *Slate* tabi Walā ti ọmọ kekeke ko gbọdọ lọ mọ ni Şukuru isisiyi, papa ni *C.M.S Girls' Seminary*. Gbogbo nkan şa, ayaşebi nwọn ba kọ sinu iwe (*Excercise books*). Nipa şişe bayi, ọgọrọ owo lo ti şofo sori a nra *Exercise books*. *Slate* tabi Wala wulo pupọ ju iwe lọ fun ọmọ Şukuru, ko si mu inawo tiàn-tián kan dani.

Ju gbogbo rẹ lọ, Şukuru ko pọ to nilẹ yi, bẹni a ko şai ri awọn diẹ nilu to ni lati yan saka diẹ kuro ninu owo olowo, owo ẹni ti nwọn jẹ gaba ıc lori loni.

Nitori ọtẹ nikan ni ẹ şe lowo lọwọ: ẹnyin olowo Eko?

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI-AJANAKU.

---

## Thanks for Sympathy.

MRS. THEODORA ADU on behalf of herself and family hereby return thanks to all friends and acquaintances who have by personal calls, letters, and otherwise sympathised with them in the loss they have recently sustained by the death of their beloved son, cousin and brother, EDWARD TAIWO O[illegible]YIKU, who departed this life at 2, Scale Square, Lagos on the 13th instant.


ILE-ÒWÒ OYINBO ALALUMỌGAJI.

# John Holt

NI ỌJA WỌNYI FUN TITA

Sarotu "Alasia"

Keke-ologere (Elerin)

Keke-Ologere (*Rudge Whit-Worth*)

Panu Iborule

Awo

Awo-abomafo

Eja-abomafo

Iyefun

Sulfuri

Efun

Alum

Oda-dudu

Orisirisi Oda-ikunle

Iso

Panu-kiko'le

Isana (Atuko)

Ẹ bere ni Şabu JOHN HOLT ni Opopo-nla, ni Eko.

"*Ebani*" ni ede-waya ti ẹnikẹni le tẹ si wọn nibikibi ni Eko tabi ni Ilu miran ni *Nigeria*.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, MARCH 29, 1924.

## OHUN TO ṢORO LOJU EGUNGUN ÀWỌ̀N TI BO O.

Kẹ̀lẹ́kẹ̀lẹ́ Ilu nrọwọ gbẹna lara igi; bi a sọ lẹnu oṣu diẹ to kọja pe ọrọ ẹjọ Ilu yio jẹ Akan bayı, ṣaṣa ni awọn ara wa to le gba eyi gbọ; gidipã a o tilẹ ri awọn ti yio sọ pe ki a lọ "ko Ifa wa danu" nitori iru ero bẹ; ṣugbọn loni nkọ? Ọlọrun ko wa fihan gbangba pe Giri lẹhin aṣõtọ ni On, A kọ̀ má ti ikà lẹhin; bẹ lori: mimu alafia wa sori ohun to ti nṣe ọkan ẹni ni hila-hilo lati ọpọlọpọ ọdun sẹhin, kò gba Baba ni iṣẹju kan lati fun ni, ojulowo-sẹria ti Adajọ da ni Alamisi ọsẹ to kọja, fi eyi han gedegbe. Ti ilu t'ayọ, o ju bẹ lọ; ori ko ni on ma b'ọrun duro.

Ṣiwaju are nla-nla yi, kini awọn ẹlomiran ko ti fi ẹnu nwọn sọ tan? Diẹ ninu awọn enia apakeji ko jẹ kumoyo tan nwọn ko nsọ bõbõ pe "Iṣẹ (*Poverty*) ko nwa enia, ṣugbọn ẹnikẹni to ba nwa iṣẹ oniyẹn ko ma sinmi" kete ki nwọn to gbe ilẹkun tì kọ ni oluwarẹ ti r'aye sọrọ maṣalubarika yi, ki la so de'bi "iṣẹ"? A nsọrọ atata Eko rẹ nsọ m'aro, "ẹniti ko to Oṣodi o nṣeṣe Ipọsu! bẹ laiye ri; Ikoko ko sa mọ pe on ma jẹ ata. Ki la sọ de ibi "Egungun ko l'ada," nwọn nṣako l'ọrun ni? Bi iṣẹ nwá enia, bi ko nwa enia, a fẹ ki ẹniti o sọ'rọ na bẹ ajọ rẹ wo nisinsinyi, ki o si sọ bi awọn Ilu lo wa iṣẹ ni tabi awọn papa ti nwọn ti ilẹkun Ile Ọlọrun; dajudaju gbogbo awọn to ṣe iranlọwọ titi rẹ ni nwọn ti tọrọ iṣẹ yi fun ara wọn, nitoripe "Ẹni d'eru l'eru ntọ:" a ki ba ti sọ robẹ si ọrọ aṣitani yi bikoṣepe a fẹ ki ẹniti a gbọ pe o sọ ọ mọ pe agba kan ko si ninu Irungbọn hihu.

Ju gbogbo rẹ lọ a dupẹ iṣẹgun keji yi ti o tun ṣoju ẹmi.

Bawo ni iṣẹgun ti a di'bo—a-kọ di'bo ti yẹ ilu to logunjọ oṣu *September* ọdun to kọja, ti gbogbo rẹ tu to ba. Ẹ tun wo iṣẹgun keji ti o tun de fun ilu logunjọ kanna ti oṣu yi; larin oṣu mẹfa si ara wọn, ti ojo si pẹtu si ekini-keji? Bẹ gẹgẹ si ni olubori iṣẹgun Ẹkẹta tun mbọ. Iwọ ọkawe yi, ko ye ọ ndan? Iṣẹgun to ju iṣẹgun lọ, eyini ni nigbati Ọbangiji Ọba Ogo ba rọ Gomina wa lọkan ti o ba si pe Eleko pada si'po rẹ bi da-nga. A! bawo lọjọ na yio ti ri o, Ẹnikeji, kai! Ọbaọjọ ni yio jẹ lọjọ na, asiko na nbọ tete, o si de tan.

Ẹmi ati Ilera lo ju, ki Ọlọrun ma ṣai fi mejeji ji-nki wa.

Awọn Iya-afin abilekọ, awọn Omidan, awọn ọmọde-mọṣọ ọkọnrin, awọn agbagba, gbogbo wa ko ni mọ igbati ayọ yio fi kun ọkan wa lọjọ na ti a o si m'orin kọ nigbati a ba nta ilẹ ni ipa wọn-in fun ijo lakọ-lakọ ti Gbadamọsi ọga awọn Oni'lu yio ma kan õgun ṣàṣà ṣà nigbati o ba nsọ kọkọrọ si'lu fun t'ewe t'agba pe:—

Eleko o, Afinju Ọba
Eleko o, Afinju Ọba
Afinju Ọba to f'ọla re'ra
Eleko nbọ lọna
Ọmọ iyà lo ma p'Ọba kosi!!!

Ki Edumare ma ṣai ṣe "To" si ọrọ yi. Aṣẹ!!!

---

### Thanks for Interest.

MR. SAMUEL PAUL of Apapa and his wife LADUNNI beg to return thanks to friends who contributed towards the bulky amount presented to them for loss sustained through fire on 21st February last.

ṢEUN, ṢEUN!!!

Ọgbẹni SAM PAUL ti Apapa ati LADUNNI aya rẹ dupẹ pupọ lọwọ awọn ọrẹ ati ojulumọ ti o da owo jọ fun wọn nigbati ile wọn jo ni ọjọ kọkanlelogun oṣu *February* to kọja.

---

A special Sermon on

**"The Captain and the Captive"**

at the Church of the Brotherhood

tomorrow at 7 p.m.

All are welcome.

## FACTS AND FIGURES

### THE MOHAMMEDAN CRISIS GIVEN A DECENT BURIAL.

#### End of the Masquerade!

The Eleko Question and the Mohammedan Quarrels—these are the two crises that for many years past have been impeding the progress of this town and are largely responsible for disquietude and social as well as political unrest in this part of our great dependency. As such, it is an occasion of no little importance when on Thursday the 20th day of March (1924) a burial—decent and legal if not *military* (for policemen lined up the precincts of the Court)—was given one of these crises.

A fight is never settled until it is settled well; and, that the decision of Sir Fredrick Van der Meulen has dropped the veil closing up the final scene of the Mohammedan Quarrels is a fact which goes without saying unless an appeal is lodged by the defendants which has not come to our knowledge as we write—and even then a straight road to a final close-up is definitely and clearly marked.

"It has been made plain to both" says His Excellency Sir Hugh Clifford in his Address to the Legislative Council, "that this is a matter which concerns only those Mohammedans who are resident in Lagos, and that any settlement that may be reached must be achieved by mutual arrangement, but *without* any interference by the Government, whose sole interest in this regrettable dispute is the *maintenance of law* and order. Litigation arising out of this dispute has now been begun in the Supreme Court."

The law is no respecter of persons and we are gratified that feelings of satisfaction at the decision of the Court are being expressed by the larger section of the community.

We sincerely hope the small group of dissatisfied minority will rest in peace. The table has now turned and at long last the law has taken its course. The axes of God grind slowly but they grind exceedingly small. Who of us is not surprised at the turn things have taken especially when we recollect the troubles taken by the Hon. J. Egerton Shyngle and Mr. Herbert Macauley to effect a mutual settlement without success. The idea was commonly expressed that one side *cannot* be defeated one side is specially *favoured* by . . . . and what not but we are highly gratified that this shall have to be knocked out of some brains these days. The masquerade is now ended and the doctrine of one side being *unconquerable*, though their cause be wrong, falls flat like Dagon before the Arch of the Lord!!!

You can fool some people all the time; you can fool all the people for some time; but you cannot fool all the people all the time!!!

ADEKANBI.

---

### Elegbata Street and Lagos Town Council.

Anybody passing Oke Arin and Dawodu's place will no doubt be struck with the improvement and the construction of gutters in this vincinity.

What always puzzles us is the half and half way in which the above Council carries on this kind of work.

Sometime last year they erected some gutters in Elegbata Square, and instead of extending those gutters to Elegbata Street, and on to meet Olowogbowo gutter they stopped; it appears the Authorities of the above-named Council forget or actually neglect this part of the town entirely; the result is, immediately there is any heavy rain, this Street is absolutely impassable and the water remains there for an hour or two, and in some parts it breathes Mosquitoes etc. Immediate relief is really necessary and as other parts of the town we are prepared to pay improvement rate, if proper Street light, and gutters are erected.

We are confident in Mr. Webb, the Town Engineer whose only aim is to do his best for us and also whose long experience in this kind of Job is a guarantee. We trust in his immediate action, and only pray him to give us his time by visiting Elegbata Street and relieve us of the above-named trouble.

ALAWIYE

---

Ṣabu Magbaralewọn,
205, Bamgbose Street,
EKO.

Si *Editor* "Eko Akete"

Mo tumba o!

Anu ṣe mi pupọ lati sọ fun nyin pe Ṣẹkiri Ẹlẹtan kan tọ mi wa ni ọjọ kẹta oṣu yi ni ibi iṣẹ mi nibi, tobẹ ti o fi tan mi ti o si sọ fun mi pe on ni oriṣiriṣi ọja ni ile on pe ki nkalọ lati lọ ra. Mo si sọ pe ko si aye fun mi lati lọ si ibikibi ni irọlẹ bayi, ṣugbón Ọlọrun-Ọba nikan lo mọ ohun ti o wa lo fun mi lọjọ yi tobẹ ti mo fi tẹle lọ si ile rẹ pẹlu owo £13 o o ni apo mi. Nigbati mo si de ibẹ, nibẹ ni mo ba enia meji nigbati mo si wọle pẹlu wọn, wọn si tilẹkun mọ mi, tobẹ ti wọn fi lọ owo yi gba lọwọ mi laita ọja kankan fun mi. Mo si pe awọn ọtẹlẹmuyẹ lati ṣe iranlọwọ fun mi lati gba owo yi lọwọ wọn ṣugbọn lori gbogbo rẹ nṣe ni awọn ogbole wọnyi tun fẹ fi ọran ti emi ko mọ ọwọ ti emi ko mọ ẹsẹ rẹ kọ mi lọrun, nwọn ko si sọ nkan meji ju pe emi wa ba wọn ta tẹtẹ lọ. Aiye re o, jẹjẹ mi ni mo joko ti iṣẹ mi o, ti wọn wa gbe ọran yi kọ mi lọrun.

Eyi ti mo ri niyi o

Emi ni tiyin
JOSIAH O. ỌṢINNUSI,
Aṣoju Ṣabu Magbaralewọn.

---


## Notice of Removal.

Barrister O. Jibowu removed from No. 55, Broad Street, to 58, Palm Church Street, Lagos.

---

AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones, Fitting and Sewing Machines.

*Workshop*:—20, WILLIAMS STREET, LAGOS.

**Charges Moderate.**

# LARGE STOCK

OF

# NEW GOODS

AT THE

# Lever Store

# ỌRẸ

## Ẹ LỌ RA NKAN EASTER NYIN NI ṢABU

# R. LOMAS & CO.

### 80 & 192, BROAD STREET.









Nwọn ṣẹṣẹ ni oriṣiriṣi ọja ni tita fun awọn Ajiṣafẹ ati awọn Ọmọge ni ọpọku ọyọku, awọn bi Aṣọ ati Ibọsẹ Ṣẹda, Bata-totilẹ, awọn Aṣọ Yọmini, Akẹtẹ loriṣiriṣi, Awọtẹlẹ, Collar Lekeleke, Ties ati awọn Ọja miran.

Ẹniti o ba gbọn, yio wa si Ṣabu wa mejeji na, a o si fi ọpọ Ọja to ti jire su u; bi ẹ ba fẹ ohun kankan, ẹ sa bere rẹ; " b'o nfó ma ba ẹ lọ " ọja wa bi aba.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | do. | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. H. W. Stacey |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ereko | do. |
| 7 p.m. | do. | Bro. S. O. Stowe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | Rev. S. A. Pearse |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. Dan. O. Mould |
| 7 p.m. | do | Bro. D. A. Ogunbiyi |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. W. K. Fafunwa |
| 7 p.m. | do. | Rev. M. B. Newton |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. A. Lalẹye |
| 7 p.m. | do. | Bro. M. I. O. |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Bro. A. M. Williams |
| 6.30. p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinyla |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 6 a.m. | Zion | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 4.30 p.m. | do. | Rev. I. O. Oyekunle |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. J. F. Oshodi |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. J. R. Williams |

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. S. M. Phillips |
| 6 p.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. F. Oshodi |
| 6.30 p.m. | Bro. Ladejo Motoye |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. | Respect'ble Bro. Adelani Gbogboade |
| 7 p.m. | Prof. Adeoye Deniga. |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM**

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.) |

**ZION CONGREGATIONAL.**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Rev. Suptd. S. A. Coker |
| 4 p.m. | do. | do. |

**SALVATION ARMY.**

| | | |
|---|---|---|
| 10 a.m. | Glover Memorial Hall | Capt. A. A. da Costa |
| 7 p.m. | do. | Lieut. Col. George H. Souter |

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọṣẹ yi ni eyi :—

EKURỌ

£15 10 0—£16 fun *ton* kan.

EPO.

£26—£27 fun *ton* kan.

COCOA.

£18—£20 fun *ton* kan.

---

KANO.

ẸPA.

£12 10 0 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.

Hides 5d fun lb kọkan.

# R. S. JAMESON,

## Licensed Auctioneer & Appraiser,

Broad Street, LAGOS.

***Prompt, reliable and intelligent Service.***

Property real and personal sold and valuations made for Probate.

Low rates of Commission and immediate settlements.

# ILE IFI ỌJA AWỌN ENIA PAMỌ SI LAILEWU.

Nigbati Ọja rẹ ba de lati Ilu Oyinbo, ti o si ni ẹ lara lati san owo Ibode lori wọn, awa yio ba ọ gba Ọja na, a o si ba ọ ṣe opo iwe gbigba wọn ni'bode.

Ti o ba si fẹ gba Ọja rẹ na lọwọ wa, iwọ maṣe ṣopo ati gba gbogbo wọn lẹkan bikoṣe eyiti ipa rẹ ba kọkọ ka na lati sanwo 'bode fun.

Iwọ yio ri pe ọna yi na ẹ lẹhin ju pe ki o lọ t'ọrun bọ igbese lọ!

Ẽra ko ni ra Ọja rẹ na ti o wa ni itọju wa.

Abẹ abo Agbowo-ode Ọba ni ile Ifi ọja awọn enia pamọ si lọdọ wa wà.

Igbakigba ti Ọja rẹ ba tun de, ti owo ba si pọ lọwọ rẹ lati gba wọn, sa lọ ri Ọgbẹni yi:—

**JAMESON,**

Ni Opopo-nla,

Leti Ile Dr. O. Sapara, I.S.O

l'Eko.

## H. S. Freeman

(Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials Films, Post Cards, Views etc., etc. on hand.

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office* :—106, TOKUNBO STREET, LAGOS.

*Telegraphic address* :—"FREEDE" LAGOS.

P. O. Box 495.

---

### ILE OWO KADUNA

...o mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamo) L'Eko.

Awa ni orișiriși Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ ...upu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" ...wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 l' a ti wa lẹnu ișẹ yi, ...wọn ọja wa si to ọja o ni igba pọun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma ...e'ro; a si nra awọn "eku" Kẹkẹ-...ogere, oni-pupu-pupu, ati Ẹ...ọ-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun șe ti a si tun nta ...wo pọ̃, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ...ti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe șọwọ si Olotu Ile-owo ...:—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ...ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.

---

### CLEARANCE SALE.

Ladies and Gents Shoes, Panamas, Velours, Felt Hats, Shirts, etc. etc., at OLUFUNMI STORE, 4, Kano Street, (Oyigbo market) Ebute Meta.






4/6 each.

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to *buy* always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz :—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor :—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS :—Cash with Orders.

---

## The Nigeria Commercial Training Institute.

ESTABLISHED JANUARY 1924.

The above Institute offers students an opportunity to undertake its Training in Short-hand, Typewriting and Civil Service English.

Further particulars can be obtained on application to :—

J. OLOYEDE DAVIES,
*Principal and Proprietor.*
10, Upper Offin Lane,
Lagos, Nigeria.

TERMS :—
Absolute satisfaction with results, or money refunded.

# A. KESSLER,

7, Labinjo Lane. P.O. Box 459.

Sample Show Room.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
The German Trading House,
Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine.

as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Decent Wristlet Watches sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

Lion Beer (Pilsener Light) 30/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite Champagne per case £3. 5. 0.

# JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variet[y] at 50, Dosunmu Street, Lagos, a[t]

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile [...] ẹṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹb[...] iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, [...] iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa nin[u] ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o [...] ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Taṭambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Olọwọ—agaga Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o [...] fẹ ẹ ni *lọnu* a lẹ ta a fun ọ, Iṣana Al-poti fun tit[a] kọ si bi a ti nṣe wọn. Orişirişi ọja lo wa lọw[o] wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tin[...] nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọ[j] rekoja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka m[i] kạ mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja i[...] wa, rin wa si ile oja wa.

Iye owo won:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan, 2/6d, 3/-, 4/-, 5/0d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin oku[n] kọwe ṣowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBẸ & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lago[s].
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis.*
Idumagbo, Eko.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, Broad Street.

Wabiwosi orişirişi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fu[n] wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orişiriş[i], ogun Ẹda, ogun arun aşiri, ogun Arẹmọ[...] ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogu[n] Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko l[e] mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ b[...] idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wonyi wo nib[i] ti a gbe nta wọn.

Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.